dura nigba gbogbo fun yin, ki ẹyin lè duro ni pípé ati ni kíkún ninu gbogbo ifẹ Ọlọrun. (Kol 1:7; Rom 15:30; Filp 3:15.)

13. Nitori mo jẹri rẹ̀ pe, o ni itara pupọ fun yin, ati fun awọn ti o wà ni Laodikea; ati awọn ti o wà ni Hierapoli. (Kol 2:1.)

14. Luku, oniṣegun olufẹ, ati Dema ki yin. (2 Tim 4:10,11; Film 24.)

15. Ẹ ki awọn ará ti o wa ni Laodikea, ati Nimfa, ati ìjọ ti o wà ni ile rẹ̀. (Rom 16:5.)

16. Nigba ti a ba sì ka iwe yìí laarin yin tán, ki ẹ mu ki a kaa ninu ìjọ Laodikea; ki ẹ̀yin pẹlu si ka ẹ̀yí ti o ti Laodikea wá.

17. Ki ẹ si wi fun Arkippu pe, "Kiyesi iṣẹ Iranṣẹ ti iwọ gba ninu Oluwa, ki o sì ṣe é ni kikún." (Film 2; 2 Tim 4:5.)

18. Ìkínni nipa ọwọ́ emi Paulu. Ẹ maa ranti ìdè mi. Ki oore-ọfẹ wà pẹlu yin. (Amin.) (1 Kor 16:21; Heb 13:3; 13:25.)

52

# AWỌN ARÁ TESSALONIKA KINNI

**(A.D. 54)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, sí ijọ awọn ara Tessalonika, ninu Ọlọrun Baba, ati ninu Jesu Kristi Oluwa: Oore-ọ̀fẹ́ si yin, ati alaafia. (2 Tess 1:1; 2 Kor 1:19; A.A. 16:1; 17:1; Rom 1:7.)

**Paulu ndupẹ fun gbogbo wọn lọwọ Ọlọrun.**

2. Awa dupẹ lọwọ Ọlọrun nigba gbogbo fun gbogbo yin, awa nṣe iranti yin ninu adura wa; (2 Tess 1:3; Rom 1:8,9.)

3. Ni àìsinmi ni awa nranti iṣẹ́ igbagbọ yin ati làálàá ìfẹ́ ati suuru ìrètí yin ninu Oluwa wa Jesu Kristi, niwaju Ọlọrun ati Baba wa; (2 Tess 1:11; 1:3.)

4. Nitori pé awa mọ yíyàn yin, ará, olufẹ ti Ọlọrun;

5. Nitori ihinrere wa kò wá sọdọ yin ni ọ̀rọ̀ nikan, ṣugbọn ni agbara pẹlu, ati ninu Ẹmi Mimọ, ati ni ọpọlọpọ igbẹkẹle; bi ẹ̀yin ti mọ iru eniyan ti awa jẹ laarin yin nitori yin. (2 Tess 2:14; Kol 2:2; 2 Tess 3:7.)

6. Ẹ̀yin sì di aláfarawé wa, ati ti Oluwa, bi o tilẹ jẹ ninu ipọnju pupọ ni ẹyin fi gba ọ̀rọ̀ naa, pẹlu ayọ̀ ti Ẹmi-Mímọ́; (1Kor 4:16;11:1;A.A.13:52.)

7. Ti ẹ̀yin si jẹ́ apẹẹrẹ fun gbogbo awọn ti o gbagbọ ni Makedonia ati Akaia.

8. Nitori lati ọdọ yin lọ ni ọ̀rọ̀ Oluwa ti dún jade, ki i ṣe ni kìkì Makedonia ati Akaia nikan, ṣugbọn ni ibi gbogbo ni ìhìn igbagbọ yin si Ọlọrun tàn kálẹ̀; tobẹẹ ti awa kò ní ohunkohun lati tún sọ mọ́. (Rom 10:18; 1:8; 2 Tess 1:4.)

9. Nitori pe awọn tikarawọn rohìn nipa wa, iru igbanisọ́dọ̀ ti a ni laarin yin, bi ẹ̀yin sì ti yipada si Ọlọrun kuro ninu ère lati maa sin Ọlọrun alààyè ati otitọ; (1 Kor 12:2; Gal 4:8.)

10. Ati lati duro de Ọmọ rẹ̀ lati ọrun wá, ẹni ti o sì jí dide kuro ninu òkú, ani Jesu naa, ẹni tí o gbà wá kuro ninu ibinu ti nbọ. (2 Pet 3:12; A.A. 2:24; Rom 5:9.)

ORI 2.

**Iṣẹ́ Paulu laarin awọn eniyan.**

NITORI ẹ̀yin tikarayin mọ̀, ará, irú ìbẹ̀wò wa si yin pé ki i ṣe lásán; (1 Tess 1:5,9.)

2. Ṣugbọn lẹhin ti awa ti jìyà ṣaaju, ti a si ti lò wá ni ìlò ìtìjú ni Filipi gẹgẹ bi ẹ̀yin ti mọ̀, àwa ní ìgbóyà ninu Ọlọrun wa lati sọrọ ihinrere Ọlọrun fun yin pẹlu ọpọlọpọ ìjàkadì. (A.A. 16:22; 1 Tess 1:5; Filp 1:30.)

3. Nitori ọ̀rọ̀ ìyànjú wa ki i ṣe ti ẹ̀tàn, tabi ti iwa àìmọ́, tabi ninu àrékérekè: (2 Kor 7:2.)

4. Ṣugbọn bi a ti kà wá yẹ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá bi ẹni ti a fi ihinrere lé lọ́wọ́, bẹẹ ni awa nsọ; ki i ṣe bi ẹni ti nwu eniyan bikoṣe Ọlọrun, ti ndan ọkàn wa wò. (2 Kor 2:17; Gal 2:7; 1:10.)

5. Nitori awa kò lo ọ̀rọ̀ ìpọ́nni nígbàkan rí gẹgẹ bi ẹ̀yin ti mọ̀, tabi ìbòjú fún ojukokoro; Ọlọrun ni ẹlẹ́rìí: (A.A. 20:33; Rom 1:9.)

6. Bẹẹ ni awa kò wá ògo lọdọ eniyan, ìbáàṣe lọdọ yin, tabi lọdọ awọn ẹlomiran, bi o tilẹ̀ jẹ́ pe a lè ti fẹlá lori yin bi awọn aposteli Kristi. (2 Kor 4:5; 1 Kor 9:1,2.)

7. Ṣugbọn awa nṣe pẹ̀lẹ́ lọdọ yin, gẹgẹ bi abiyamọ ti ntọ́jú awọn ọmọ oun tikararẹ̀: (ẹsẹ 11; Gal 4:19.)

8. Bẹẹ, gẹgẹ bi awa ti ni ifẹ inu rere si yin, inu wa dun jọjọ lati fun yin, ki i ṣe ihinrere Ọlọrun nikan, ṣugbọn ẹmi awa tikarawa pẹlu, nitori ti ẹ̀yin jẹ ẹni ọ̀wọ́n fun wa. (2 Kor 12:15; 1 Jhn 3:16.)

9. Nitori ẹ̀yin ranti, ará, iṣẹ ati làálàá wa: nitori awa nṣe làálàá lọsan ati lori, ki awa má bàà di ẹrù rù ẹnikẹni ninu yin, nigba ti a nwaasu ihinrere Ọlọrun fun yin. (A.A. 20:34; 2 Tess 3:8; 2 Kor 12:13.)

10. Ẹyin sì ni ẹlẹri, ati Ọlọrun pẹlu, bi awa ti wà laarin ẹyin ti o gbagbọ ni mímọ́ ìwà ati ni ododo, ati ni àìlẹ́gàn: (1 Tess 1:5; 2 Kor 1:12.)

11. Gẹgẹ bi ẹyin sì ti mọ bi awa ti nba olukuluku yin lò gẹgẹ bi baba sí awọn ọmọ rẹ̀, a ngba yin niyanju, a ntù yin ninu, a si nkọ́ yin. (1 Kor 4:14; ẹsẹ 7.)

12. Ki ẹyin lè maa rìn ni yiyẹ Ọlọrun, ẹni ti o npe yin sinu ijọba ati ogo oun tikararẹ̀. (Ef 4:1; 1 Pet 5:10.)

**Bi awọn eniyan ṣe gba Paulu.**

13. Nitori èyí ni awa ṣe ndupẹ lọwọ Ọlọrun pẹlu ni aisinmi, pe nigba ti ẹ̀yin gba ọ̀rọ̀ ti ẹ̀yin gbọ́ lọdọ wa, ani ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ẹ̀yin kò gba a bi ẹni pé ọ̀rọ̀ eniyan, ṣugbọn gẹgẹ bi o ti jẹ nitootọ, bi ọ̀rọ̀ Ọlọrun, eyi ti o ṣiṣẹ gidigidi ninu ẹ̀yin ti o gbagbọ pẹlu. (1 Tess 1:2; Gal 4:14.)

14. Nitori, ará, ẹ̀yin di aláfarawé awọn ìjọ Ọlọrun ti nbẹ ni Judea, ninu Kristi Jesu: nitori pe ẹ̀yin pẹ̀lú jìyà iru ohun kannaa lọwọ awọn ara ilu yin, gẹgẹ bi awọn pẹlu ti jìyà lọwọ awọn Ju: (A.A. 17:5; 2 Tess 1:4.)

15. Awọn ẹni ti o pa Jesu Oluwa, ati awọn woli, wọn sì tì wá jade: wọn kò si ṣe eyi ti o wu Ọlọrun, wọn si wà lodi sí gbogbo eniyan: (A.A. 2:23; 7:52.)

16. Wọn kọ̀ fun wa lati sọrọ fun awọn Keferi ki wọn lè là, lati maa sọ ẹ̀ṣẹ̀ wọn di kíkún nigbagbogbo: ṣugbọn ibinu de ba wọn titi de opin. (A.A. 9:23; 13:45, 50; Matt 23:32.)

**Iṣẹ́-iranṣẹ Timoteu laarin awọn eniyan.**

17. Ṣugbọn, ará, awa ti a gbà kuro lọdọ yin fun sáà kan ni ara, ki i ṣe ni ọkàn, pẹlu itara ọpọlọpọ ni awa ṣe aniyan ti a si fẹ gidigidi lati ri oju yin. (1 Kor 5:3; 1 Tess 3:10.)

18. Nitori awa fẹ lati tọ̀ yín wá, ani emi Paulu lẹẹkinni ati lẹẹkeji: Satani si dè wa lọ́nà. (Rom 15:22; 1:13.)

19. Nitori kinni ireti wa, tabi ayọ̀ wa, tabi adé ìṣògo wa? Ki ha ṣe ẹ̀yin ni niwaju Jesu Oluwa wa ní bíbọ̀ rẹ̀? (2 Kor 1:14; Filp 4:1; 1 Tess 3:13.)

20. Nitori ẹ̀yin ni ogo ati ayọ̀ wa. (2 Kor 1:14.)

## ORI 3.

NITORI naa nigba ti ara wa kò gba a mọ́, awa rò pe o dara ki a fi awa nikan sẹ́hìn ni Ateni; (ẹsẹ 5; A.A. 17:15.)

2. Awa si rán Timoteu arakunrin wa, ati iranşẹ Ọlọrun ninu ihinrere Kristi, lati fi ẹsẹ̀ yin múlẹ̀, ati tù yin ninu niti igbagbọ yin: (2 Kor 1:1; Kol 1:1.)

3. Ki a má şe mu ẹnikẹni yẹsẹ̀ nipa wahala wọnyií: nitori ẹ̀yin tikarayin mọ̀ pe a ti yan wa sinu rẹ̀. (A.A. 9:16; 14:22.)

4. Nitori nitootọ nigba ti awa wà lọdọ yin, a ti nsọ fun yin tẹ́lẹ̀ pe, awa o ri wahala; gẹgẹ bi o sì ti şẹ, ti ẹ̀yin si mọ̀. (A.A. 20:24; 1 Tess 2:14.)

5. Nitori eyi, nigba ti ara mi kò gba a mọ́, mo si ranşẹ ki emi lè mọ̀ igbagbọ yin bóyá olùdánwò ti dán yín wo lọ́nàkọnà, ati làálàá wa lè ti jásí asán. (1 Kor 11:3; Gal 2:2.)

**Paulu gbọ ìròhìn ayọ̀ lati ọdọ wọn.**

6. Şugbọn nisinsinyìí ti Timoteu ti ti ọdọ yin wá sọdọ wa, ti o sì mu ihinrere ti igbagbọ ati ifẹ yin wá fun wa, ati pe ẹ̀yin nşe iranti wa ni rere nigbagbogbo, ẹ̀yin si nfẹ gidigidi lati rí wa, bi awa pẹlu si ti nfẹ lati ri yin: (A.A. 18:5; 1 Tess 1:3.)

7. Nitori eyi ará, awa ni ìtùnú lori yin ninu gbogbo wahala ati ipọnju wa nitori igbagbọ yin: (2 Kor 1:4.)

8. Nitori awa yè nisinsinyìí, bi ẹ̀yin ba duro şinşin ninu Ọluwa. (Filp 4:1.)

9. Nitori ọpẹ́ kinni awa lè tun maa dá lọ́wọ́ Ọlọrun nitori yin, fun gbogbo ayọ̀ ti awa nyọ nitori yin niwaju Ọlọrun wa; (1 Tess 1:2.)

10. Ni ọ̀sán ati ni òru ni awa ngbadura gidigidi pe, ki awa lè ri oju yin, ki a si şe àşepé ẹ̀yí ti o kù ninu igbagbọ yin? (2 Tim 1:3; 2 Kor 13:9.)

**Adura Paulu fun wọn.**

11. Njẹ ki Ọlọrun ati Baba wa tikararẹ, ati Jesu Kristi Oluwa wa, şe amọ̀nà wa sọdọ yin. (2 Tess 3:5.)

12. Ki Oluwa si maa mu yin bisi i, ki ẹ si maa pọ̀ ninu ifẹ si ọmọnikẹji yin, ati si gbogbo eniyan, gẹgẹ bi awa ti nşe si yin: (1 Tess 4:1,10.)

13. Ki o baa lè fi ọkàn yin balẹ̀ ni àìlábùkù ninu Ìwà mímọ́ niwaju Ọlọrun ati Baba wa nigba àtiwá Jesu Kristi Oluwa wa pẹlu gbogbo awọn eniyan mímọ́ rẹ̀. (1 Kor 1:8; 1 Tess 2:19; 4:17.)

## ORI 4.

**Ọ̀rọ̀ iyanju lori ìwà mímọ́.**

NI àkótán, ará, awa nbẹ yin, awa si ngba yin niyanju ninu Jesu Oluwa, pe bi ẹ̀yin ti gbà lọwọ wa bi ẹ̀yin ìbá ti maa rin, ti ẹ̀yin ìbá sì maa wu Ọlọrun, ani gẹgẹ bi ẹ̀yin ti rìn, ki ẹ̀yin lè maa şe jù bẹẹ ati jù bẹẹ lọ. (Filp 1:27; 1 Tess 2:12; Kol 1:10.)

2. Nitori ẹ̀yin mọ iru àşẹ ti a ti pa fun yin lati ọ̀dọ̀ Jesu Oluwa.

3. Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, ani wíwà ní mímọ́ yin, pé ki ẹ̀yin takété si àgbèrè: (1 Kor 6:18; Kol 3:5.)

4. Ki olukuluku yin lè mọ̀ bi oun ìbá ti maa şàkóso *ohun-èlò rẹ̀ ni ìwà-mímọ́ ati ni ọlá; (1 Kor 7:2; 1 Pet 3:7; 2 Tim 2:21; Heb 13:4.)

5. Ki i şe ni sişe ifẹkufẹ, gẹgẹ bi awọn Keferi ti kò mọ Ọlọrun: (Kol 3:5; Ef 4:17; 1 Kor 15:34.)

6. Ki ẹnikẹni má şe rekọja, ki o má sì şe şẹ arakunrin rẹ̀ ninu nkan naa: nitori Oluwa ni olùgbẹ̀san ninu gbogbo nkan wọnyìí gẹgẹ bi awa ti kìlọ̀ fun yin tẹ́lẹ̀, ti a si jẹri pẹlu. (1 Kor 6:8; Heb 13:4.)

7. Nitori Ọlọrun kò pe wa fun iwa èérí, şugbọn ni ìwàmímọ́. (Lef 11:44; 1 Pet 1:15; 1 Tess 2:3.)

8. Nitori naa ẹnikẹni ti o ba kọ̀, kò kọ eniyan, bikoşe Ọlọrun, ẹni ti o fun yin ni Ẹmi Mímọ́ rẹ̀ pẹlu. (Rom 5:5.)

**Ọ̀rọ̀ Iyanju lori ifẹ ati işẹ şişe.**

9. Şugbọn niti ifẹ awọn ara, kò tún yẹ ki ẹnikẹni kọwe si yin: nitori a ti kọ́ ẹ̀yin tikarayin lati ọdọ Ọlọrun wá lati maa fẹ ara yin. (Rom 12:10; 1 Tess 5:1.)

---

(4) *(Ohun-èlò yìí le túmọ̀sí ohun meji pataki (1) şişe akóso ara ẹni kuro ninu àgbèrè tabi (2) şişe eto igbeyawo wa lọna iwa-mimọ ati ni ọlá.)

10. Nitootọ ẹyin si nṣe e si gbogbo
awọn ara ti o wà ni gbogbo Makedonia
ṣugbọn awa nbẹ yin, ará, pe ki ẹyin
maa ṣe bẹẹ siwaju sii. (1 Tess 1:7;
3:12.)
11. Ati pe ki ẹyin maa dù gidigidi
lati gbé jẹ́, lati maa gbọ́ ti ara yin, ki ẹ
maa fi ọwọ́ yin ṣiṣẹ́, gẹgẹ bi awa ti pàṣẹ
fun yin; (Ef 4:28; 2 Tess 3:10–12.)
12. Ki ẹyin lè maa rìn irin ẹ̀tọ́ si
awọn ti nbẹ lode, ki ẹ má lè ṣe alaini
ohunkohun. (Rom 13:13.)

**Ọ̀rọ̀ itunu nipa awọn Ayanfẹ tó sùn.**

13. Ṣugbọn awa kò fẹ́ ki ẹyin jẹ òpè,
ará, niti awọn ti o sùn, pe ki ẹ má ba-
nujẹ gẹgẹ bi awọn iyoku ti kò ni ireti.
(Ef 2:12.)
14. Nitori bi awa ba gbagbọ pe Jesu
ti kú, o sì ti jinde, gẹgẹ bẹẹ ni Ọlọrun
yoo mu awọn ti o sùn pẹlu ninu Jesu
wà pẹlu ara rẹ̀. (1 Kor 15:13,23.)
15. Nitori eyiyiì ni awa nwi fun yin
nipa ọ̀rọ̀ Oluwa, pe awa ti o wa laaye ti
a si kù lẹhin de wíwá Oluwa, bi o ti wu
ki o ri ki yoo ṣaaju awọn ti o sun. (1
A.Ọba 13:17; 20:35; 1 Kor 15:51,
52.)
16. Nitori Oluwa tìkárarẹ̀ yoo
sọkalẹ̀ lati ọ̀run wá pẹlu ariwo àṣẹ pẹlu
ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè
Ọlọrun; awọn òkú ninu Kristi ni yoo si
kọ́kọ́ jinde: (Matt 24:31; 1 Kor 15:23;
2 Tess 2:1.)
17. Nigba naa ni a o sì gba awa ti o
wà láàyè ti o sì kù lẹ́hìn soke pẹlu wọn
sinu ìkùukùu awọsánmà, lati pade
Oluwa loju ọ̀run: bẹẹ ni awa o sì maa
wà titi bẹẹ lọdọ Oluwa. (1 Kor 15:52;
A.A. 1:9; Ifh 11:12; Jhn 12:26.)
18. Nitori naa, ẹ maa fi ọ̀rọ̀ wọnyìí
tu ara yin ninu.

ORI 5.

**Dide Oluwa lẹẹkeji.**

SUGBỌN niti akoko ati igba
wọnyìí, ará, ẹyin kò tún fẹ ki a kọ
ohunkohun si yin. (A.A. 1:7; 1 Tess
4:9.)
2. Nitori pe ẹyin tikarayin mọ̀ daju-
daju pe, ọjọ Oluwa nbọ̀wá gẹgẹ bi olé
ni òru. (1 Kor 1:8; 2 Pet 3:10.)
3. Nigba ti wọn ba nwi pe, alaafia ati
ailewu; nigba naa ni iparun òjijì yoo
de sori wọn gẹgẹ bi irọbí ti nde bá
obinrin ti o lóyún; wọn ki yoo si le
sálà. (Hos 13:13.)
4. Ṣugbọn ẹyin, ará, kò sí ninu
òkùnkùn, ti ọjọ naa yoo fi dé ba yin bi
olè. (A.A. 26:18; 1 Jhn 2:8.)
5. Nitori gbogbo yin ni ọmọ imọlẹ,
ati ọmọ ọ̀sán: awa ki i ṣe ti òru, tabi ti
òkùnkùn.
6. Nitori naa ẹ má ṣe jẹ ki a sùn, bi
awọn iyoku ti nṣe; ṣugbọn ẹ jẹ ki a
maa ṣọ́nà ki a si maa wà ni airekọja.
(Rom 13:11; 1 Pet 1:13.)
7. Nitori awọn ti nsùn, a maa sùn ni
òru; ati awọn ti nmutipara, a maa mu-
tipara ni òru. (A.A. 2:15; 2 Pet 2:13.)
8. Ṣugbọn ẹ jẹ ki awa, bi a ti jẹ ti
ọ̀sán, maa wà ni airekọja, ki a maa gbe
ìgbàyà igbagbọ ati ìfẹ́ wọ; ati ireti
ìgbàlà fun aṣibori. (Ef 6:14,23,17.)
9. Nitori Ọlọrun yàn wa ki i ṣe fún
ibinu, ṣugbọn lati ní igbala nipasẹ Jesu
Kristi Oluwa wa. (2 Tess 2:13,14;
Rom 14:9.)
10. Ẹni ti o kú fun wa, pe bi a ba jí,
tabi bi a bá sùn, ki a lè jumọ wà láàyè
pẹlu rẹ̀. (2 Kor 5:15.)
11. Nitori naa ẹ maa gba ara yin
niyanju, ki ẹ si maa fi ẹsẹ̀ ara yin mulẹ,
ani gẹgẹ bi ẹyin ti nṣe.

**Ohun àìgbọ́dọ̀ máṣe.**

12. Ṣugbọn awa nbẹ yin, ará, lati
maa mọ awọn ti nṣe làálàá laarin yin, ti
wọn si nṣe olori yin ninu Oluwa, ti wọn
si nkìlọ̀ fun yin; (1 Tim 5:17; Heb
13:17.)
13. Ki ẹ si maa bu ọlá fun wọn gidi-
gidi ninu ifẹ nitori iṣẹ́ wọn. Ẹ si maa
wà ni alaafia laarin ara yin.
14. Ṣugbọn awa nbẹ̀ yín, ará, ki ẹ
maa kilọ fun awọn ti i ṣe aláìgbọ́ràn, ẹ
maa tu awọn aláìlọ́kàn ninu, ẹ maa ran
awọn alailera lọ́wọ́, ẹ maa mu suuru
fun gbogbo eniyan. (2 Tess 3:11; Rom
14:1.)

15. Ẹ kiyesi i, ki ẹnikẹni máṣe fi buburu san buburu fun ẹnikẹni; ṣugbọn ẹ maa lépa eyi ti i ṣe rere nigba gbogbo, laarin ara yin, ati laarin gbogbo eniyan. (Rom 12:17; 1 Pet 3:9; Gal 6:10; 2:13,14; Rom 14:9.)
16. Ẹ maa yọ̀ nigbagbogbo. (Filp 4:4.)
17. Ẹ maa gbadura ni àìsinmi.
18. Ẹ maa dupẹ ninu ohun gbogbo: nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun ninu Kristi Jesu fun yin.
19. Ẹ má ṣe pa iná Ẹmi. (Ef 4:30.)
20. Ẹ má ṣe kẹ́gàn isọtẹ́lẹ̀.
21. Ẹ maa wadi ohun gbogbo dájú; ẹ di èyí ti o dara mú ṣinṣin. (1 Kor 14:29; 1 Jhn 4:1.)
22. Ẹ maa takete si ohun gbogbo ti o jọ ibi.

**Ọ̀rọ̀ ìparí.**

23. Ki Ọlọrun alaafia tikararẹ sọ yin di mímọ́ patapata; ki a si pa ẹmi ati ọkan ati ara yin mọ́ patapata ni àìlábùkù ni ìgbà wiwa Oluwa wa Jesu Kristi. (Rom 15:33.)
24. Ọlododo ni ẹni ti o pè yín, ti yoo sì ṣe e. (1 Kor 1:9.)
25. Ará, ẹ maa gbadura fun wa. (Ef 6:19.)
26. Ẹ fi ifẹnukonu mímọ́ ki gbogbo awọn ará.
27. Mo fi Oluwa mu yin bura pé, ki a ka iwe yìí fun gbogbo awọn ará. (Kol 4:16.)
28. Ki oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi wà pẹlu yin. Amin.

53

# AWỌN ARÁ TESSALONIKA KEJI

**(A.D. 54)**

ORI 1.

**Ọrọ Ikini.**

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, sí ijọ Tessalonika, ninu Ọlọrun Baba wa ati Jesu Kristi Oluwa : (1 Tess 1:1; 2 Kor 1:19; A.A. 16:1.)
2. Oore-ọfẹ si yin, ati alaafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba, ati Jesu Kristi Oluwa. (Rom 1:7; 1 Kor 1:3.)

**Idupẹ.**

3. Iṣẹ wa ni lati maa dupẹ lọwọ Ọlọrun nigbagbogbo nitori yin, ara, ani gẹgẹ bi o ti yẹ, nitori pe igbagbọ yin ndàgbà gidigidi, ati ìfẹ́ olukuluku yin gbogbo sí ara yin ndi púpọ̀; (1 Tess 1:2; 3:12.)
4. Tobẹẹ ti awa tikarawa nfi yin ṣògo ninu ijọ Ọlọrun, nitori suuru ati igbagbọ yin ninu gbogbo inúnibíni ati wàhálà yin ti ẹyin nfaradà. (2 Kor 7:14; 1 Tess 1:3; 2:14.)

**Ìyànjú lati farada ìjìyà.**

5. Eyi ti i ṣe àmì idajọ ododo Ọlọrun ti o dájú, ki a lè kà yin yẹ fun ijọba Ọlọrun, nitori eyi ti ẹyin pẹlu ṣe njìyà: (Filp 1:28; 1 Tess 2:14.)
6. Bi o ti jẹ pe ohun òdodo ni fun Ọlọrun lati fi ipọnju gbẹ̀san lara awọn ti npọ́n yín loju. (Kol 3:25; Ifh 6:10.)
7. Ati fun ẹyin, ti a npọ́n loju, isinmi pẹlu wà, nigba ifarahan Jesu Oluwa lati ọrun wá ninu ọwọ́ iná pẹlu awọn angẹli alagbara rẹ̀. (1 Tess 4:16; Jud 14.)
8. Ẹni ti yoo san ẹ̀san fun awọn ti kò mọ Ọlọrun, ti wọn kò si gba ihinrere Jesu Oluwa wa gbọ: (Rom 2:8; Gal 4:8.)
9. Awọn ẹni ti yoo jìyà iparun ainipẹkun lati iwaju Oluwa wa, ati lati inu ogo agbara rẹ̀. (Filp 3:19; 2 Pet 3:7; 2 Tess 2:8.)